**Akiyesi**

A nfẹ awọn enia ti yio ma ba wa ta I r o h i n Imolẹ ni awọn ilu wonyi Igbo-Ora Shaki Iseyin Ezuwa Lalate AkurẹOndo Ado- Ekiti Gbogan Fiditi Oyo Ẹdẹ Ikorodu Shagamu Ilaro ati Ilora.

Ẹ kowe si:-
Olotu IROHIN IMOLẸ
16, Bamgb oye Street,
Lagos.

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Lakaye oro**

Iru ila ni ila ma so, Ajule ina, ko ni yo yo pupa. Bi ina ba npupo bẹlẹẹ, bi ojo si ndudu bolojo ohun to ba jo wunren la fi n w e ara wọn, Agiliti ko jọ ọmọ Akata, afibojo ko jọ ọmọ Gid gidi

VOL. VI No. 331 MONDAY MAY 28 — JUNE 3 1962 KOBỌ MEJI (2)

# Ija Ibadan ka ma ri lo dun, Ija gba odo, o gba ọlọ, nwọn ja titi nwọn ṣẹ ọpa Adehun

IBadan:- Ija to sele larin awon Igbimo Assembly nigboro ilu Ibadan lojo Jimo kose nI, enu ko irohin, bi o ba nwo ako ese ti won fi nyo ehin ara won, iwo ko je duro. to be ge nse ni eje bo okan ninu awon Minister ti a npe ni Kesington Momo.

Ninu ija yi, ọpa ti Ijọba Gẹsi fi ba Ijọba Iwọ Orun se Adehun ni a gbọ pe, nwọn jan mọle, o si ṣẹ si meji Ni agogo mẹsan abọ, i p a d e ti nwọn koko se ni lati gba wipe gbogbo ilẹ na fi tọkan-tọkan gba Oloye Adegbenro ni Premier

Bi nwọn ti mbẹ lẹnu Igbimọ yi, bẹni Ọkunrin kan ti o njẹ Oke ara Ogbomoṣọ ki gbe larin Igbimọ bayi pe, ye! ye! ye! Oke Ibadan gbina, ọrọ na wa di bi o ko le lọ, ki o yago fun mi, bẹni, aga bẹrẹ si fo l o r i wọn, Olori si bẹrẹ si du ori rẹ.

Pẹlu bi ijọgbọn ti bẹ silẹ ninu ile Igbimọ toyi awọn ara igboro ilu Ibadan ko gbọ ohun kan, olukuluku si gba ọna iṣẹ rẹ lọ. Nigbati awọn Ọlọpa ṣakiyesi pe ija na fẹ le rekoja ẹnu ala, ni awọn Ọ l ọ p a ba yinbọn Pamọlẹkun lati fi tu wọn ka (Tear Gas)

Prime Minister sọ wipe, bi on ko ba ko awọn Ọlọpa ṣodi, ko daju pe on yio le da ija na duro. Bẹni ija na si mudo. Ṣugbọn ija ẹlẹkeji tun bẹrẹ nigbati ọ g b ẹ n i Tinubu@sọpe, ayafi bi ọgbẹni Adeleke Adedoyin ba fun awọn laye ninu igbimọ na.



## ỌLỌLA TAFA BALEWA TI PE IPADE IJỌBA—APAPỌ NITORI ỌRỌ NA

Ọlọla Tafa Balewa sọ fun gbogbo aiye gbọ pe on ti pe ipade igbimọ Alapapọ lati se ipade pọ ni ọjọ Atalata, ṣ u g b ọ n ọrọ ẹjọ na ti de iwaju Adajọ Kotu Ganran

Nigbati ija ori ekeji bẹrẹ nile igbimọ nişoju a w ọ n Ọ l ọ p a lo se. A gbọ pe Tinubu mu agogo kan dani bi ti awọn Serafu bi o ba ti lu agogo na gbogbo awọn ọmọ ẹ g b ọ N. C. ti o wa nibẹ yio pariwo pe "A ko gba!" bẹni nwọn si da ijoko na ru

Ṣugbọn awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ pe arawọn jọ lẹhin na lati jiroro lori ohun to sẹlẹ ati iru ọna ti awọn yio tun gbe ọrọ na gba. Awọn enia pataki to wa wo'ran ni ile igbimọ na ni, Oloye Awolọwọ, T. O. S. Benson J. S. Mecwen Oloye Fani Kayọde so fun Oga Ọlọpa wipe bi Oga Ọlọpa ba se i l e igbimọ na ni isekuse on ni yio fori gbe ẹbi rẹ

Agbọ wipe awọn Imale ati Kiriyo ti pinu lati se adura lori ọrọ na, ki Ọlọrun le ba wa pẹtu si.

ADVERTISEMENT NO. 76.

## KERE O

OFIN TI A NFI NA OWO ATIJỌ (WEST AFRICAN CURRENCY BOARD NOTES & COINS) DI PI PARE

A fẹ lati ran gbogbo ẹnyin enia leti wipe ati ọjọ kini oṣu July, 1962 (oṣu keje ọdun yi) gbogbo owo Atijọ patapata eyi ni owo Pepa ati owo Şile titi de ori Epini yio kuro. A ko ni le lo wọn gẹgẹ bi Ofin ni ilẹ Naijiria.

Eyi ni wipe lati ọjọ kini oṣu keje (July) ọdun yi, owo Atijọ wọnyi koni wulo fun sisan owo fun Iṣẹ Aje ni jake jado ilẹ Naijiria - fun apejuwe, aikoni gba fun Ọja rira tabi fun Ọja tita ninu Ọja ati Ṣọbu.

Gbogbo ẹniti o ba ni owo Atijọ wọnyi lọwọ tabi ni ipamọ yala ni pepa tabi ni Şile ni lati tara lọ se paşi parọ owo wọnyi ni Bank ki Bank fun owo titun eyiti C e n t r a l Bank ti Naijiria fi sita ni nkan bi ọdun kẹta sẹhin, ti a si na lọwọlọwọ yi ki ọjọ kini oṣu keje ọdun yi (July) to to. Ofẹ ni gbogbo Bank yio parọ owo wọnyi fun yin.

*JOHN BEACH*
*Deputy General Manager.*

*Central Bank of Nigeria,*
*Lagos.*

# Ọrọ Olotu

## "ATI KOJE BOLORIṢA LỌWỌ O WA KÙ BABA ẸNITI YIO BỌ"

NI IJẸJỌ, ỌJỌ KỌKANLELOGUN OṢU YI, ALHAJI ADEGBENRO BỌ SI AYE OLOYE AKINTỌLA, O DI PRẸMIA IWỌ ORUN. GOMINA IPINLẸ IWỌ ORUN ỌBA ALAIYELUWA ỌNI TI IFẸ NI O BURA FUN.

A ba Alhaji Adegbenro yọ, o kuoriire, Oye a mọ ori.

Ọjọ ti o di Prẹmia o da wa loju pupọ ninu awọn ọmọ Ipinlẹ Iwọ orun yio ranti ọrọ oke iwe yi "Ati kojé boloriṣa lọwọ, o ku baba ẹniti yio bọ" Ohun Oloye Akintọla ni yi nigbati o sọrọ si ọrọ gbohungbohun. Eyi ni o fi pari ọrọ rẹ lori ikede ti o ṣe nipa gige owo Koko. Anu ṣe ni nisisiyi pe Igbagbọ ti oloye Akintọla ni ki i ṣe bẹ. Aigbọtoriṣa lo koje boloriṣa lọwọ, ajigbọtoriṣa na ni o si nbẹ o.

Imọran wa nisisiyi si Alhaji Adegbenro ni pe ki o ya fi eyi kọ ọgbọn. Ẹni kan ki i jẹ awa de, ajeje ọwọ kan ko gbẹru dori, agbajọ ọwọ la fi ngbẹru dori ẹni. Igbẹhin "afi emi, afi emi" ki i dun, ṣugbọn igbẹhin "afi emi, afi emia" adun ni. Nwọn ti koje boloriṣa Alhaji lọwọ nisisiyi, ko mọ pe ti on ba nda igbo ṣe lẹhin oro, nwọn yio bọ oye kuro lọwọ on.

## Gomina Agba pada wa sile lori irin ajo re



Nnori ede koyede ti o be sile larin egbe Action Group eyiti o ṣẹlẹ lakoko ti Gomina Agba, Olola Dokita Nnamdi Asikiwe mbe lori Isimi Olofe, lo ṣe pa isimi olofe ne ti, ti o si yara pada wa si ẹnu ise re, nitoripe bi a o ba da ẹkọ fun Aja eni, nisoju wno eni lo nse.

Nisisiyi o ti de, o nwo bi oro ti nlo, nitoripe oye ni Agba nwo, Kojti soro kan nitoripe kojti de ibiti o ure,

# Yẹyẹnatu!

## O NI YẸYẸ EKO

Yẹyẹnatu:— Olotu, ṣe mo sọ fun yin pe nko fẹ ki Suberu lọ si Ibeṣe lọ ṣiṣẹ.

Olotu:— Hẹn! ki ise gbogbo ẹni ṣiṣẹ ni Ibeṣe ni Ibeṣe kẹ.

Yẹyẹnatu:— Irọ, Gbogbo Ibeṣe, Ibeṣe ni ile wọn.

Olotu;— Ṣe bi Suberu si ti pada tabi kilo tun de?

Yẹyẹnatu:— Ko gbowo iṣẹ bọ kẹ

Olotu:— Tabi o di Ibeṣe lọtọ? Haha! ki enia ṣiṣẹ, ko ma gbowo.

Yẹyẹnatu:— O gba a nkẹhin ṣa o

Olotu:— Bawo? O tun pada lọ ni?

Yẹyẹnatu:— Mo tẹle ni kẹ, Ngbati mi ki nse igan

Olotu:— Bawo lo ṣe wa gba a?

Yẹyẹnatu:— Ṣẹ ri bi nse dọhun, mi ni ko fọga na han mi. Bi mi ṣe ri, mi ki i dada. Mi wa redi sọtun, mi redi sosi, mi ṣa nfi idi mi jo Konga ṣa, ni



Olotu:— Ha! ha! O nfi idi rẹ peṣẹ si lọrun.

Yẹyẹnatu:— Ha! Ṣe mi ti mọ pe ori ẹnyin Okunrin ma nyi ni ti ẹ ba ti ri Onidi kuṣini

Olotu:— Yẹs kẹ, o purọ

Yẹyẹnatu:— Mi wa ni "Ẹ jọwọ, aburo mi yi lo sọ pe ọ ko fun on lowo iṣẹ"

Olotu:— Hẹn! O pe Suberu laburo rẹ?

Yẹyẹnatu:— Igba to ti di Ibeṣe, kilọ fẹ ki npe e?

Olotu:— O ma ṣe o.

Yẹyẹnatu:— Oga ni. Ha! nko mọ pe aburo nyin ni. Ṣe ẹ jẹ ka rira ṣa? Mi ya sare dahun, mi ni, ofin ni yẹn kẹ, pe bawo, Mi tun rẹju si i

Olotu:— Iyẹn ni pe ko ri rẹ nigbati o nsọrọ yẹn ni tabi kilo tun min kẹ?

Yẹyẹnatu:— Hẹ! eke yin, Ṣe bi ẹnyin na mọ nkan to fẹ ka rira fun?

Olotu:— O-ho, o ti yemi

Yẹyẹnatu:— Abi o, lo ba sanwo fun Suberu, mi wa ni, Ha! ha! ẹ ko ni ṣe wa lalejo ni

Olotu:— Ha! ha! o tun ni ko ṣe yin lalejo kẹ?

Yẹyẹnatu:— Yẹs kẹ, igbato jẹ on loga awọn Ibeṣe

Olotu: O yes, o sa ti ni ẹ fẹ rira

Yẹyẹnatu:- Lo ba ra igo biya meji ati Stautu meji

Olotu:- Laiye Họsitẹ yi.

Yẹyẹnatu:- T'ara igo kan nsun ṣin, Mi ni o ṣe bebi. Ni nba fami ntemi o jare

Olotu:- Nko bawi ṣa, ntori o mọ ohun to ntori rẹ nawo, o fẹ gbadun idi nla ni.

*Yẹyẹnatu:— Ha! ha! Ẹ rope emi yen Igan ni, ko ni gbagbe mi laiyelaiye.*

*Olotu— Ha! kilo ṣe?*

*Yẹyẹnatu:— Nigbati mi muti tan mi ri mọto kan to nbọ wa si Eko, mi juwọ si I, o duro, m kan gbe bagi mi ni, mi wa juwọ si Ọga Ibeṣe, mi ni Wẹll, kẹ jẹ ka rira nirọlẹ o.*

*Olotu.— Ha! ha! ha! Lo ba wọ mọto?*

*Yẹyẹnatu:— Ni mọto ba ṣi. Mi ba ni Balẹ Ibeṣe, ka rira ni irọlẹ. Bayibayi o. Lo ba duro o nge ika jẹ. Mi lo ma ṣe o lara Ibeṣe.*

## Akintọla taku wọnle pe, ko si kini kan ti yio ti oke wa gbe ọlọ

Nigbati Gomina Ibadan Ọlọla Adesoji Aderẹmi fi ofin kealelogbọn, ese kewa ninu iṣelu ile wa yo Oloye S. L. Akintola kuro ni oye Asiwaju awon Oṣelu (Premier) ni ipinle Iwo orun nile Naijiria, nwon tilekun ile iṣe re.

Agbo wipe ilekun ti nwon ti yi, awọn enia kan lo fi agbara silekun na, lẹhin ti nwọn ti fi ipa silẹkun na tan, ni Oloye Akintola ati die ninu awon alatilehin re nwon lo sinu ile iṣẹ ti nwon sina lagbara. Die ninu awon alatilehin na ni wonyi:

Ọba C. D. Akran, J. O. Adigun, Oloye S. A. Tinubu Rosiji Agbaje ati Akintoye A gbo pe Oga Olọpa kan rin lo ba Akintola, o wipe, "Oga! ofin ti nwon fi so nyin di Asiwaju Oselu, nwon ti pare. Oloye Akintola bere pe, "Tani pare?" Oga Olopa na si dahun pe Gomina Ibadan lo pare

A gbo irohin wipe nisoju Oga Olopa kan ni nwon ṣe nfọ ilẹkun ile ise Premier lehin ti nwon ti tilẹkun na.

# IBADIARAN BI IBETA NILU ADO-EKITI

ADO-EKITI Obinrin Adelebo kan ti oruko re nje Ibadi-aran ni a gbo irohin pe o bi Ibeta si Ile Ilamo ti a npe ni Maria Asumpt Catholic Maternity Home nilu Ado-Ekiti. Obinrin na je iyawo Okunrin Agbe kan ti o ngbe opopo Jako Street nilu Ado-Ekiti meji ninu awon Ibeta na je Okunrin okan yoku si je Obinrin.

Oko Obinrin na ti oruko re nje Jinadu ti se eni ogbon odun ole meta (33 years) so wipe gegebi asa ibedale won, on ti lo fun Oba Ewi Ado Ekiti Oba Aladesanmi ni irohin ayo na.

# Oluko Agba to se Afowora fi Ewon osu mejidinlogun se ifa je

Josiah Egwu, tise omo odun medogbon ti o je Oluko Agba fun ile Eko Alakobere ti a npe ni LOCAL AUTHORITY SCHOOL ti Afougiri ni eba ilu Umahia ni a gbo pe Adajo da ejo ewon osu mejidinlogun fun esun ise aiyederu ati pe o ji owo ti o to Adofa ponun ati sile merindinlogun pelu kobo mejo (£110: 16s: 8d) ninu owo Igbimo Ibile ti a npe ni odida Anyanwu Country Council ni agbegbe ilu Bende larin osu keje si kejila odun to koja yi.

Bakanna ni a si tun gbo pe Oluko Agba yi gba owo 11 esi we lowo awon omo ile Eko na ti o si lo fun anfani ara tire, o tun yi ise lati fi gba owo.

# Ina Lentiriki pa Omode kan

Omode kekere kan ti ko ju Omo odun merinla lo ni a gbo Irohin wipe Ina lentiriki pa si ebute ilu Port harcout (wharf) nigbati omode na fe gbiyanju lati koja lori okun Ina lentiriki ti o wa nile.

A gbo wipe won ti gbe oku Omode na lo si ile Iwosan nilu Port harcourt Olopa si nwa awon obi omodena.


BERE OJULOWO EGBOGI AWON FARANSE TI A NPE NI

## "UROXAL"



Fun Itoju tabi fifo Apo Ile Ito Kidney-Bladder fun Okunrin ati Obinrin bi awon amodi wonyi ba nyo o lenu Ehin didun ori ile ito tabi ito-jijo enia, ito rirun, riku-ruku Pipon rirun, lakuregbe, iba-radi wiwo, orunkun, owo, ese, Eji-ka wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju aiko le gbe ara konkon tabi kiakia didaji loru nigbakugba, ati orisirisi awon aisan tabi amodi ba wonyi ni egbogi aje bidan ni yio wo san lara re ni kia kia ti alafia yio si de si o. Meji re ko ni ilu Naijiria nitorina sora ki awon eleru tabiawon Oni robiro-robi ma ta orisi omiran ti ko ni lari fun e, mase gba a rara o! Owo re je Sile Mejo abo 8/6d owo Oko Sile meji abo (2/6d) Bere Egbogi yi ni sobu awon Saro ti won npe ni:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchuch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA

WATERLOO MEDICINE STORES
11A. FAGBEWESA STREET OSHOGBO

ATI NI SOBU IBADAN:-
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BOLA


# Enyin omo araiye ema je ka ba woli je fun Olorun nitoripe awon Woli Alafose tipo nile Aiye.

Lati Owo PROPHET KOGBEREGBE.

Owe ni eyi je fun gbogbo, enia ti egun ba sope on kori gonto ponto na ni on kori egun, Mo ki enyin ojise Olorun. E je ka sera wa ki oruko Oluwo ma ba di isoro odi si lari awon keferi nitoripe opolopo awon Woli lonse agbere ti Olorun ko fe nitorina ni Oluwa se wipe agbere wa larin yin iru agbere ti a ko gburo larin awon keferi pe okan ninu yin fe aya baba re.
(1,KORINTI ORI 5, ESE 1, Opo Woli le nse afose ti Olorun ko lowo si.

Ejowo e mase jeka so ise Olorun di ti ara wa mo fe ki e mo pe Ile aiye ko se gbe beni ode orun ko se lo gbogbo eyin woli ilu eko e je ka sora wa o ka ma ba jorun gba-ko ro wo ko to gbe opa re ile aiye ni awawi gbe wa ko si awawi lorun o OLI, PASITO, BISOBU, elose kan ko ni lo laijiya ka ma ri e ma kiyesi awon eke woli ati awon eke Alaji ti o to yin wa ni nu awo aguntan sugbon apanije Ik oko ni won ninu Ese won ya si iwa ika, enu won ya si isokuso, gbogbo awa Woli ni Olorun yio da lejo, E so won ni enyin o fi mo won.



WOLI KOGBEREGBE

Enia a ma ka eso ajara lori igi egun ogan tabi eso Opoto lara ewon, Gegebi eti gbo gbogbo igi ti ko ba so eso rere a o ge lule a o si wo so sinu ina, nitorina nipa eso won le o fi mo won, ki se gbogbo eniti npe mi ni Oluwa Oluwa ni yio wo ile Ijoba Orun MATTEU 7 ESE 15.

Woli ati Alaji e je ka ka ranti wipe Oluwa so wipe Iwo kogbodo ni Olorun miran pelu mi nitori Olorun owu ni mi ti o mbe ese baba wo lara omo lati iran Kinni titi de iran keta, Mo fe ki gbogbo awon ojise Olorun mo wipe opo ni koni ri Ijoba Orun nitori aya alaya, Opo longba adura pelu afose lenu re.

Mo so fun enyin Woli Olorun e mase de irun ode awon bayi ko si a wa wi kan lorun Ha! Ye! Opo awa Woli i yio ro ejo aya re yio si gbe, E se ti owo kekere loje lodo Olorun E se ti agbere lo buruju niwaju Eleda Orun ohun aiye E jowo iwo Woli eke e lo wa ise se, lona Apapa.

Mo lo si idale loju kan ni ilu Oshogbo emi ko mo enikan ninu ilu na, mo de si ile adura kan, Ojukoju nwon bere si fi wo, mi Woli Obinrin kan ko ki wa ra-ra o Okunrin kan fun wa ni owo miran 2/6 sugbon emi ko gba owo na.

Nitori wipe opolopo awon Woli eke ti lo ba ilu na je lo je ki won fi oju be wo mi- Jesu maje ki a di enia egbe lodore.

# OGUN ITAJA

**E ma pelowo Oja yin sinu iwe Irohin Imole nigba gbogbo. O si tun kun fun Itan aladun.**

# Malu ti ko ni Iru Ọba Oluwa ni nba le Eşinşin

OBERẸ LATI ỌSẸ TOKOJA

Ki a ma fa ọrọ gun gbogbo ọmọkunrin lọ ko si ẹniti o daruko ọrọ yi.

Aburo Ojo wa lọ si ile oku, o ge apa oku ti o sẹsẹ ku o si fi si abẹ agbada o lọ si ọdọ ọmọ ọba, bi o ṣe de ibẹ o sọ fun ọmọ Ọba pe nkan akikanju ti on ti ṣe ni pe on ati ẹgbọn on ti lọ nko ile ọba ilu mgbati takuta ọba si mu ẹgbọn on, on bẹ lori, on si gbe lọ, nigbati Ọba so oku rẹ kọ, on rọ awọn Olusọ oku na yọ on si gbe oku ẹgbọn on na.

Bi ọmọ se i. di mu o na owo oku s, o di mu gbagi aburo Ojo si ba oju ferese jade, Ọmọ ọba, ni awọn Igbati o jẹ okunkun ko mọ pe apa enia lasan ni o ti mu o si kigbe baba rẹ nigbati awọn t a n Ina nwọn ri pe apa enia lasan ni ẹru si ba oba.

## Latifu Bọlaji Babalọla

AKỌWE AGBA ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Ni akoko yi o su ọba, o si pinnu Idariji lati dariji ẹni na ti o ni ọgbọn to bayi o lu agogo o si sọ fun gbogbo ilu pe bi ẹni na wa si iwaju on yio sọ di ọlọla.

Ngbati aburo Ojo gbọ ọrọ yi ko gba ọba gbọ o sọ fun Iya rẹ Iya na ni ko gbọdọ da i wo ti i o fẹ be oruko awọn jẹ ni o ni awọn yio ti Ajala sẹ pe ki o sọ pe on ni awọn yio si ko die ninu awọn awo ni ẹru ọba fun Ajala ki o fi han ki ọba le gbagbọ.

Nwọn ni awọn ko gba wipe Ọba yio se bi o ṣe wi nitoripe o daju pe pipa ni yio pa ẹni na.

Nikukuru, nwọn ti Ajala nwọn di ẹru fun o si lọ si ọdọ Ọba o sọ fun o ni on ni ẹni na ọba yọ mọ o paro akisa ara rẹ o fun nile o si fi ọmọ rẹ fun.

Bi aburo Ojo ṣe gbọ ọrọ yi ara ta o sọ fun Iya rẹ Iya rẹ si sọ fun pe ki o sare lọ ba ọ b a ki o sọ fun Şugbọn epa ko boro mọ buruku ti nwọn fẹ se fun ọmọ oku ọrun ti di ire fun un.

Ọba ko gba ọrọ aburo Ojo gbọ ri iwọn igbati o ti ri ẹru rẹ lọwọ Ajala o binu o si pa aburo Ojo o ri o wa lati tan on jẹ.

Bayi ni ajala ṣe di Ọlọla, Ọlọla ọkọ ọmọ Ọba.

# Aja gbe ẹsẹ enia bẹ Ẹnu o si ngbe salọ

Aja kan ma gbo pe won ri ti o gbe ese enia lo enu ti o si nsalo ni ọpọpọ kan ninu Kafanchan ni ose ...

Obinrin kan ti o nlo si Oja ni aja gbo pe o ri aja na nigbati o nsalo pelu ese enia lenu re. ... Aja ... ko ... Okunrin ti o nle Aja ... gbe ese enia na lo ... Olopa nibe ni nwon ti ... Lakubu.

Omobinrin ... Kafanchan ... Aja ... Onigbo ... Ibaji ...

# EJO SAN IYAWO-ILE KAN PA

Ni ilu Ogoja ni a ti gbo irohin wipe Ejo san Iyawo ile kan pa ... IYAFIN MARIA OKO.

Ejo na le Maria titi de nkan bi ibuso meta lati inu ... emi.

Maria lo si Oko re lati lo ... Odo ti o mbe leba Oko re ... Ejo dudu ... Oko re ki Maria ... Ejo yi si buje ... o si ku.

# ẸNITI O TAPA SI AŞẸ

O BẸRẸ LATI OJU EWE KẸTA

Eyi fun ọpọlọpọ enia ninu pupọ. Nitoripe ki işe ara Ọşun nikan lo nda owo ori, bẹni ki i ş i şe nitoripe Oloye Akintọla jẹ ọ m ọ Ọşun ni o şe di olori Ijọba tabi Igbakeji olori Ẹgbẹ. Ohun ti o gbe Oloye Akintọla de oye wọnyi nipe o ti nşe ẹgbẹ pẹlu ododo ati aitapa si aşẹ ẹgbẹ fun ọjọ pipẹ. Nisisiyi ti ko si tun şe Ẹgbẹ pẹlu ododo, ti on na si gba ẹbi, ti ẹgbẹ ba gba ipo lọwọ rẹ ko yẹ ki alayinsi tun ma ba ọrọ jẹ.

ẸKỌ NLA.................ŞUGBỌN

Nisisiyi ẹniti Şango ti toju rẹ wọle ko ni bu Ọba Koso mọ. Lati ọmọde de agba ẹgbẹ Afẹnifẹre, o daju pe gbogbo wọn ni yio fa ara wọn leti. Nitoripe bi aşẹ ẹgbẹ ba le ẹ sori Igbakeji Olori, tani yio ha tun ku ti ko le şe le lori.

WO IYOKU NI OJU EWE KEJE


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE NI:—

# RICHALET

FUN ARUN EJẸ ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọọi Işe rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo K o k o r o buruku ti o ba wa ninu "EJẸ ARA" bi Mọnọmọnọ.

Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TỌNIKI Ejẹ ti wọn si nta kakiri, ni owo pọọku, adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo. Iyẹn se e w ọ awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npota ni ile yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ iruẹ awọn egbogi bawọnyẹn a ma ba ojulowo egbogi atata ti aranşe fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti a w ọ n Tatambulu si Itali jẹ mọ daju pe bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọn yi le se ọ Lakuregbe, orisirisi Inarun, Ojuşuşu tabi didun, Jedi-Jedi, Ako Iba, arun Edoki, Aya didun, Tanpara ati Ekuru laya

Ara riro, Lapalapa Egbo ẹsẹ Amọdi Apo ile itọ, ẹhin didun tabi ibaradi r i r o pẹlu egbogi Risaleti a ma pa gbogbo kokoro buruku ti o wa n i n u ẹjẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu. Şa dan Igo rẹ kan wo lara rẹ dajudaju iwọ yio ma rohin rẹ f u n ẹlomiran pẹlu nigbakugba.

Bere ni Şobu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchuch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET OSHOGBO

ATI NI ŞOBU IBADAN:-
IŞE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

## ẸNITI O TAPA SI AṢẸ

O BẸRẸ LATI OJU EWE KẸTA

Fun wakati meji abọ ni Oloye Akintọla fi sọ ọrọ rẹ lati fi se alaye lẹhin igbati wọn ka ẹsẹ rẹ fun. Sugbọn gbogbo alaye rẹ oputa ni. Ninu adọta enia, ọkanlelogọrin ni o fi ẹnu si i pe o jẹbi, enia mọkandinlọgbọn pere ni o si ro pe ko jẹbi. Ni iwọn igbati enia to sọ pe o jẹbi si ti ti pọ ju awọn to ni o jare lọ, o ru ẹbi rẹ.

Mo gba fun ẹgbẹ Afẹnifẹre nitoripe nwọn fun Oloye ni aye wakati meji-abọ lati sọ ọrọ, ti nwọn si jẹki awọn enia sọ bi o jare tabi o jẹbi. Oloye ni oju ni awọn enia wo ti nwọn fi na ọwọ pe ohun jẹbi. Eyi le jẹ otitọ. Sugbọn o si le jẹ oju ni awọn ti o nawọ pe o jare na wo. Ekeji ọwẹ eto gẹgẹbi ilana ẹgbẹ ni nwọn ntẹle ti nwọn ko dibo ni oni bokelẹ. Bi o ba ṣe pe Oloye Akintọla mọ pe iru eto bayi ko dara, kini ṣe ti ko ti gba ẹgbẹ ni imọran lati ọdun yi ki ẹgbẹ yi da? O da mi loju pe ẹgbẹ yio ti lọ iru eto bayi lati da ẹjọ fun ọpọ ọmọ ẹgbẹ, ṣugbọn ohun ti ko ba kan ni a ki ro arojinlẹ nipa rẹ pupọ, o ma ṣe o!.

Ṣibẹṣibẹ a ko le ṣai ma bẹ ẹgbẹ pe ki nwọn dẹkun. Ko si ẹniti aṣiṣe ko le ba; ẹnikẹni ti o ba si ronupiwada o yẹ ki o ri idariji. Bi enia ko jẹ olori ijọba, o le jẹ olori ohun miran ti yio si tun ma lo ipo ọla. Nitoripe gbogbo enia ti kigbe ijapa kọja, ẹ ma jẹki nwọn kigbe ana ijapa labọ ọja.

Mo fi ọwọ ke si oloye Akintọla pe olotọ ṣọwọn. Ti o ba si jẹpe emi pa-a-pa sunmọ oloye dada ni nko ni le sọ otitọ fun. Gẹgẹbi on na si ti mọ ayinike lo laiye; oni bẹni, ọla bẹkọ. Ti oloye ba le fi ara mọ ẹjọ ti ẹgbẹ da a, o da mi loju pe ọpọ enia ni yio kan sara si i, ti nwọn yio si ke si ẹgbẹ pe ki nwọn fi oju anu wo o.

## Oluka enia lọ ka Gọmina Ipinlẹ Iwọ Orun



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọlọla Gọmina Ipinlẹ Iwọ orun Ọlọla Adesọji Aderẹmi nigbati o nfi orukọ silẹ lọdọ awọn akọwe ti o nka enia on ati awọn ara ile rẹ, ati ọmọ ati ẹbi rẹ. Ẹniti o duro lẹgbẹ rẹ ni akọwe ti o nkọ orukọ silẹ, Orukọ Akọwe na ni Ọgbẹni Ademọla.

## Alhaji Awẹlẹnjẹ tajo de Barika Oke Arafa ti o gun

IKẸJA:- Ko si bo ti ri ni Ayọ ti o gbojikan larin awọn ara ọrẹ ati ojulumọ nigbati Alhaji Abudu Wahid Awẹlẹnjẹ ba ọkọ gunlẹ pelu awọn Alhaji ti o mbọ lati Igboro Mọka.

Die ninu awọn gbajumọ ti o lọ pade rẹ ni Ikẹja ni awọn Alhaji wọnyi Alhaji S. A. T. Awẹlẹnjẹ, Baba to bi Alhaji to ṣẹṣẹ de na, Haji Bussri, Mustafa, Aṣẹṣafẹ Ṣomọpẹ Alaka, ati awọn Alufa wọnyi: Mustafa, Suailu Agba, ati kekere, Sakariyawo, Abudul Hamid, Abu Akaje.

Alfa Ishagamu, Alufa ati Alufa Abudu Lahi.


BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TONIKI TITUN TI O SESE DE TI WON NPE NI:-

"DYNAMIREN" TONIKI

EGBOGI AJEBIDAN FUN AGBALAGBA OKUNRIN ATI OBINRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haun-haun ti awọn Jamani nṣe wa fun tita ki ogun (WAR) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ, Lẹhin igbana a ko ri Irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yẹn mọ ni Ilu Naijiria, Eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn Ogbologbo Dọkita wa ni Ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye, wọn si da esi pada wipe wọn mbẹ atipe egbogi ti a nfe lọdọ wọn wa pẹlu Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mọ daju wipe ko si aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara, ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ bi arẹ ara ba mu ọ nigba-kigba fun wahala tabi iṣẹ de ti o ko ba le jẹun daradara tabi ki o ma le sun de ọkan lasan tabi loru tabi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara arẹ Eemi (Breath) inu rẹ koba gunlẹ dara dara to nitoripe iṣẹ tabi wahala ṣiṣe ko "NJE" fun awọn ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun lọ si dede adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati ṣe ara lọjọ di ọtun patapata, oju rẹ a si lọjọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe konkon nigbakugba "Arẹ" nigbakugba yio salọ patapata.

Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere ni Ṣọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchuch Street Lagos,
Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET OSHOGBO

ATI NI ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA



## Agbowo Ile

Eyi ni lati fi kede fun awọn onile ati gbogbo enia pe a ṣẹṣẹ da iṣẹ owo ile gbigba ati lati ma gba ogbologbo gbese lọwọ awọn onigbese ti o ba jẹ yin lowo kiakia. Ẹ fi iṣẹ kan dan wa wo na a o si ṣe ni aseyanju.

MANAGER
6, OJO ROAD
ODU ABỌRẸ MUSHIN.

# IWI ASIKO

LATI ỌWỌ:- Afolabi Ojelabi

## Igbẹhin Loju

Bodalẹ nla toloto ntaraka
Koloto farabalẹ, ko sai fi iyedenu
Tori ibẹrẹ kọ lonijẹ, igbẹhin lọran
Ọjọ a ba ku la mọ paiye yẹ ni
Igbẹhin loju, kasa mọ kanju
Bosika apawo, boninure nkuta
Ko ma banujẹ, igbẹhin lalayo nla
Ẹni buru bi awusa, ẹni re bi ewuro
Awusa a fakọkọ loyin, a fi igbẹhin koro
Ṣe igbẹhin ladun ewuro
Kojọ alẹ sa ṣan ju towurọ lọ
Iyen ni atata ọrọ.

Iwọ ọga agba ti ngba riba koto fun ẹni ni iṣẹ
Iwọ akọwe agba ti ngbowo lọwo alaini
Koto ba wọn waṣẹ ati jẹun
Edumare a dakẹ dajọ
Ọba oke ko ni pin ku sibi kan o daju
Ilẹ a gba osika lakọkọ
Ṣugbọn ati sun lẹbọ
Iwọ agba Onigbagbọ to ndowo ju lọsọsẹ
Ranti pe owo riba to nda ko ni ere
Owo eru, ibi, airuju lo nko ba ni
Iwọ Imale, Ladani to nba wọn di tira
Gbogbo saka rẹ otuwa ni
Ṣe igbẹhin loju
Ka lowo lowurọ, talaka lalẹ
Iyẹ kọ ni iyi ẹni
Bo lagbara loni to nfiya jẹ mẹkunnu
Bo lowo lọwọ lo njẹ ara yoku niya
Ranti pe igbẹhin loju
Ẹda ti ko yi ti ku ko koja ohun-kohun
Ogorọ oṣelu lo nfi oro si nu selu
Nwọn a bu owo onipo nla fẹni wọn ko fẹ
Nwọn a ṣe ti ẹni fẹ ti wọn silẹ repẹtẹ
Ṣugbọn ẹni gbingi oro saiye nkọ?
Bo pẹ titi ẹgi a so
Bi baba ko le e duro
A bọ sowọ ọmọ, ọmọ a si jiya ẹṣẹ
Ika iba ma ro igbẹhin, bawọ ni iba ṣe dun to
Oninu buruku iba ma ro ọla
Ṣe aiye iba ma yẹ gbogbo wa
Iwọ baba agba to mbori ọmọ ọlọmọ jẹ
Ranti pe ọbimọ funrarẹ
Ko ma lọ, ko ma bọ, o daju
Bi ko de loni, a de lọla, abọ lọran
Igbẹhin loju
Kasa mu suru kanyedenu
Atore ati ika ikan ki i gbe
Isu ko ni ta ekurọ o daju
Ohun a ba gbin la'o ka gbangba

## Akintọla fi iwe ran Ọmọ rẹ lọ silu Oyinbo

Agbọ irohin agbayanu kan wipe Ọgbẹni Akintọla kọ iwe asiri kan o mu fun ọmọ rẹ, obinrin ti o njẹ Dele ki o mu iwe na lọ fun Ọba Gesi.

Ohun ti a gbọ wipe, o kọ sinu iwe na nipe, ki Ọba Obinrin gba oye kuro lori Gomina Ibadan. Ṣugbọn bi ọmọ ti ngunlẹ silu Oyinbo lọwọ Oloye Okotie-Eboh ni a gbọ pe iwe na bọsi, Okotie-Eboh si mu iwe na fun pada, o si wa lọ mu iwe na fun Ọgbẹni Duncan Sandys. Awọn aṣoju wa ni ilu Oyinbo wa nibẹ, awọn bi Abudul Maliki, Toye Coker ati Iyafin Ọdunjọ, nwọn ko gbọ ṣwọn ko si mọ.


Ref. N° 55 PHOTO



PRICE £ 5.

WINDSOR

19, Avenue [illegible] - Cannes, France


AKIYESI

ITAN IFẸLOJU APA KẸJỌ DI ỌSẸ TO MBỌ

## Akintọla pe Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun lẹjọ siwaju Adajọ Agba

A gbọ Irohin wipe Oloye Akintọla pe Gomina Ibadan Aloye nwa Ọlọla Adesoji Aderemi lẹjọ siwaju Adajọ agba nilu Ibadan.



Adajọ Agba na Ọlọla Quashie Idum pa aṣẹ wipe on fẹ ri totun tosi awọn ẹlẹjọ yi ki o rojọ tirẹ sinu iwe ki nwọn si fi ranṣẹ si kotu. Adajọ na sọ pe on fun Akintọla layo ọjọ meje ki o fi rojọ tirẹ, ṣugbọn ọjọ meji pere ni on fun Gomina lati ro tirẹ ọjọ ti Akintọla fẹ ba Gomina na ro ni nwọnyi.

Gọmina Ibadan ko lasẹ lati yọ on kuro lori oye laijẹ wipe o gbe on lọ si iwaju Igbimọ Assembly ẹniti a nwo nisisiyi. Aworan oke yi ni Ọgbẹni Olu AyọỌla ti iṣe lọya ti o nja fun Oloye Akintọla ni Ilu Ibadan nwọn ti yọ ẹjọ na si ọjọ karun oṣu ti o mbọ.

## IPADE PATAKI FUN AWA ỌMỌ BALOGUN DELOKUN ILUGUN ABẸOKUTA

Eyi ni lati kede fun gbogbo awa Ọmọ Balogun Ilugun Abẹokuta ni Ile ati ni idale pe Ipade pataki ti a nṣe ni oṣoṣu yio wa ni ile Iyafin Felicia Balogun Maiẹ kodunmi Nọmba 83/87 Ola Ọrẹ lane Agege ni ọjọ aiku ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu kẹfa ọdun yi (10/6/62).

A fẹ ki ẹsẹ gbogbo ẹbi pe lọjọ na nitoripe a fẹ yan awọn Oloye.

AJISEGIRI (AKỌWE).

*Printed and Published by MODUPẸ PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495, Lagos Phone 21985. Olotu E. A. Adeniji 24, Oliyide Street, Odu Abore MUṢHIN.*